# ELETI OFE

'A-NJU-WON KO SE WI LEJO'

VOL XIV NO 902 LAGOS SATURDAY JAN 4. — JANUARY 10 1964 KOBO MEJI (2D)

**Orisa Aganyin Gbele!**

# Nkrumah Pade Agbako Ninu Odun Titun

ACCRA--Ọrọ bẹhin yọ! Olotu ilu Aganyin, Dokita Kwami Nkrumah pade agbako ni ibẹrẹ oṣu ọdun titun. Ni oru ana ni a gbọ wipe ẹnikan yin bọ fun ni ẹmarun bi o ti jade ninu ile ijọba ti o ngbe ni Christianborg, James Town ni Accra, bi o ti fẹ wọ mọto lọ si ode.

Irohin ṣoki ti a tun gbọ nipa pipa ti nwọn fẹ pa a na ni wipe ibọn ko baa afi ọkan ninu awọn ar ugbalẹhin rẹ ti ọta ba, ti o ku si ile iwosan ti nwọn gbe e lọ.

A gbọ wipe titi di isisiyi ko ti si ẹniti a le sọ ibiti Dokita Nkrumah alara papa wa ni Ghana. Awọn enia kan ni Dokita Nkrumah na ti ko gbogbo awọn ọmọ ati iyawo kuro ni Ghana ti pẹ nitoripe ẹru jinjin mba on na.

## Egungun Oniko Ku Silu Igbira

OKENNE-Mọto akẹru kan pa egungun oniko kan ti o nṣe ere ọdun kiri ni irọlẹ ana nibiti o gbe nle enia kiri ode.

Onirohin wa ni nibi ti egungun na gbe nsere ọdun kiri, ti o nle awọn enia kiri oju titi ni o gbe kọlu mọto akẹru ti o tẹ ẹ pa a bamubamu.

OYE NCNC DỌRAN N'IBADAN:

## Awọn Ọmọ Egbe Alakuko Di Alalikali, Aga Ati Igo Ni Nwọn Fi Nyanju Oro

IBADAN:— Rogbodiyan nla kan ti o tun bẹ silẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ni Oke Mapo ni Ibadan ni ọsẹ ti o kọja ti bẹrẹsi bi ọmọ ti balogun olori ẹgbẹ na ko ni le to. Lọjọ Abamẹta ijẹjọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ na kọ pe ipade si Oke Mapo, a gbọ wipe akufọ igo ati aga ni nwọn bẹrẹsi ju fi fọ ara wọn lori, ki awọn ọlọpa to fi ipa la wọn.

Gẹgẹbi iwe ti a ri gba lati ọdọ akọwe onirohin wa lati Ibadan nipa rogbodiyan ti o bẹ silẹ na, o ni Oloye Mọjidi Agbaje tiṣe minisita eto ikede Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni o kọ ṣe ikede wipe on fẹ ba awọn ọmọ ẹgbẹ na ti o wa ni Ibadan sọrọ lọjọ na lẹhin ti o ti ṣe abẹwo gbogbo igberiko Ibadan wo tan. Ile ipade ilu ti nwọn kọ si oke Mapo ni o gba fun ipade na.

Onirohin wa ni ko tun ye awọn ara Ibadan si bi ọrọ na ti ṣe tun yi da, ti o di wipe Oloye Fani Kayọde ati Ọgbẹni R.O. Akinjinde pẹlu awọn ọmọlẹhin wọn ni nwọn ba ninu ile ipade na, nwọn si ti fi gbogbo aga jẹko ọkan ninu awọn ọmọlẹhin Agbaje ni eyi ni o mu ki awọn fi ijoko ti awọn si ita gbangba.

O ni wara were ti awọn ṣe eyi ọkan ninu awọn ọmọ jandu ku ti o ntẹlẹ awọn Fani-Kayọde lẹhin ti bọ sita, o ni ki awọn ko ẹru awọn wọle tipa tipa. Nibi ti awọn si nfa ọrọ na lọwọ, awọn janduku ẹgbẹ rẹ ti jade s'awọn, nwọn si fi ipa ba ẹrọ-gbohun-gbohun ti awọn gbe wa lati fi sọrọ jẹ ọmọ awọn lọwọ.

A gbọ wipe ọrọ oye ọga jijẹ ni o kọ da rogbodiyan na silẹ ni iwọn nkan bi oṣu kẹfa ọdun ti o kọja ni iwọn oṣu kẹta, ọrọ rogbodiyan ... b'Ige b'Adubi, ... ọmọ ẹgbẹ Alakukọ Ibadan ni awọn fẹ Ọgbẹni Akinjide ko ṣe aṣiwaju awọn afi Ọgbẹni Adeoye Adisa.

Awọn ọmọ Ibadan ni ti awọn ... o a mọ ibiti awọn ... eri awọn pe, awọn ... ni lati mọ ibiti awọn ... mbọ, nwọn ni ọmọ ... MỌBỌLAJẸ ni O... e Akinjinde tẹlẹ ... enia ti gẹrẹ bi ... awọn mọ ... ki awọn ...

# New London House For C.M.S.

LONDON The Church Missionary Society, which now has more than 900 clergy, teachers and doctors working throughout Africa and Asia, announced plans for a new headquarters building in London yesterday, Thursday.

The new headquarters which is expected to be in use by the end of next year, will consist of a block of offices, space for meetings and consultation and place of prayer and spiritual renewal.

The Chur5h Missionary Society, was founded in 1799 to strenghten the work of the church in fifty-two dioceses in Africa and Asia, has 120 missionaries at work today in West Africa.

ELETI-OFE
(ANIJU WỌN KO ṢE WI LEJỌ)
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMS
28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-OFẸ" LAGOS
B. O. Box 467 Phone 23370
VOL XIV. -NO 902 SATURDAY JAN 4, - JAN 10 1963.

**Oro Olotu:**

# E Kiyesi Ara!

Nigbati ẹ o ba ma fi-ka iwe irohin Eleti-Ọfẹ ti ọsẹ yi, ẹ o ti sun orun ọjọ mẹta ninu ọdunrun ọjọ o le marundinlọgọta ti o wa ninu ọdun titun ti a ṣẹṣẹ bẹrẹ yi, eleyi ko di aya onirohin Eleti-Ofe na lọwọ lati ba yin jiroro lori bi ẹ o ti ṣe lo igbesi aiye yin si ninu irin ajo ti a ṣẹṣẹ bẹrẹsi wa lọ yi.

Ninu ọsẹ ti o kọja yi ni a gbọ irohin alufa-agba kan ti bẹrẹsi ṣe iwasu fun awọn enia rẹ ni ilu South Africa gẹgẹbi awọn oṣelu ode isisiyi ti nsa agbara lọtun losi LATI MA FI OFIN DI AWỌN ENIA ti awọn ba fẹ sọ otitọ lẹnu, yala nwọn jẹ ojiṣẹ Ọlọrun ni tabi adajọ-kotu.

## Omi–Inira

Oniwasu na ni eyi mu ki otitọ jinna si awọn araiye, aiye wa di rudurudu, OMINIRA KO SI, A FI OMI-INIRA, gbogbo wa wa di ota ara wa. Ọrọ na wa di bi o ba ba a, ki o pa a; bi o ko si ba a, ki o bu u lẹsẹ.

Tani le sọ wipe igbesi aiye alalafia ti awọn ba la wa rgbe ni IWỌN ỌDUN MẸDOGUN ni a ngbe nisisiyi? Irọ ni; gbogbo wa ni a wa ninu ẹru lojojumọ Awọn ti nwọn nṣe atọkun Ijọba wa paapa t ru tẹru ni nwọn fi nrin, nwọn si fi mbu omi mu.

## Owo Leke Otito

Ọrọ inu Bibeli ti sọ pato nkan ti o fa ẹru jinjin bayi. O ni, BI IWỌ BA SỌ ỌTITỌ ARA YIO YA Ọ. Ninu aiye ti a wa yi owo ti leke otitọ sisọ. Ọpọlọpọ awọn alufa Ṣọọṣi ati Mọsalasi'ni awọn mbẹru lati sọ otitọ fun awọn janma wọn nitori owo ti nwọn fẹ fun wọn.

Ara, iwọ wa ṣe ipinnu kan wipe ninu ọdun titun ti a bọ si yi otitọ ni wa ma sọ larin awọn enia, yala o jẹ bale-ile ni tabi ọmọ-ile ni, yala o jẹ ọga-iṣẹ ni tabi ọmọ-iṣẹ; yala o jẹ adajọ ni tabi ọlọpa ni ẹ.

Iwọ oṣelu paapa kini ipinnu rẹ? Tabi o ko mọ wipe gbogbo wa ni a ni lati ṣe ipinnu fun ọdun tuntun ki a si mu awọn ipinnu na ṣẹ, ki aiye le toro ki a ri ibi gbe.

Ara, ẹ ṣọra ninu ọdun ti a ṣẹṣẹ bẹrẹ yi ki a ba ma jogun iparun.

# Iwe Si Olotu

## Kini Nkrumah Fe Da?

Ẹ jọwọ ẹ la nkan ti Dokita Kwami Nkrumah, Alakoso ilu Ghana fẹ da ye wa, ojojumọ ni o nfun awọn ara ilu rẹ ni inira.

Igba kan o ko awọn ọmọ ẹgbẹ alatako oṣelu ilu rẹ si aja ile, igba miran awọn diẹ ninu awọn ọmọ ẹgbẹ tirẹ fi ọwọ tun ba, ti o tun da awọn si lọwọ an ọẹ, ti lo ni nwọn fẹ pa on.

Gbogbo awọn oniwe irohin ti nsọ otitọ fun ni ilu rẹ ni o ti le jade bamubamu. Laipẹyi ni a tun gbọ wipe o da ọga awọn adajọ agba ilu rẹ duro nitoripe ko da ẹjọ awọn enia kan ni ọna ti Nkrumah fẹ.

Kini o fẹ da ? Bi o ba je bayi ni awọn Oyinbo Gẹẹsi ti nṣe wa ki nwọn to gbe ominira le wa le wa lọwọ, on alara paapa ko ba mọ odo ti on ti da ọra si.

Emi ni
Jimọ Alao
Ladipọ St.
Mushin

## Mo Fara mo Oro Omo Abati

Emi faramọ ọrọ Ọgbẹni Ọmọ Abati ti o sọ sinu iwe Eleti Ọfẹ laipẹ yi wipe Ijọba alapa kan ti ko ni ni awọn alatako ko dara.

Bi ko ba si awọn alatako ninu ile igbimọ a ko ni ma mọ bi nwọn ti nna owo ori wa si, ofin ti o ba wu ijọba ni nwọn yio ma gbe jade si wa lori, ko ni si enibawi mọ olukuluku awọn ti a ba yan si ile igbimọ a maṣe bi nwọn ba ti fẹ.

Ẹ jọwọ ẹ ba wa sọ fun Oloye Dennies Oladebay wipe ọrọ ijọba ti ko ni orogun ko lọ ni Nigeria wa yi rara nitoripe bi ẹja ba jafara ẹja a fi ẹja jẹ lodo.

Mo duro nihin, Olotu ẹ ṣe aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
Amọda Onilu,
Pakata,
Ilorin.

YOUR SPECIALIST FOR ALL
BUILDING MATERIALS
BROSSETTE
(NIGERIA) LTD.
WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA
At your service
• STOCK
• SPECIAL ORDERS
• TECHNICAL INFORMATIONS

Olofintoto Fe Mo...

# Awon Koseku Koseye Larin Awon Omo Igbo-mina (2)

Ọgbẹni Aroworọwọn o ṣe pupọ ati mọ wipe iru awọn enia alarosọ, awọn a ri jẹ ninu maduru bayi ni lati pọ jaburata ninu awọn ti nwọn nfi ọrọ ilu jeun.

Iwe ti olotu ri gba lọwọ Aroworọwọn ọmọ Igbo-mina ni ẹ ri ka ni ọsẹ ti o kọja yi, ti mo ba wipe ki emi alara papa tẹ awọn ti mo ri gba lati ọdọ awọn ọmọ Ọffa ati Alhaji Muda Ilọrin pẹlu awọn sanmari Iludun ati awọn akẹkọ ọmọ Esiẹ, iwe yi a kun faya.

## Awon Ko Seye

Ẹ jeki a pa iyẹn ti ki nṣe ikilọ ṣoki ti mo fẹ ṣe fun ẹnyin ọmọ Igbomina nitoripe ọkanna ni wa nkan ti o ba si ba oju o ba imu. Emi Olofintoto ko wipe ki ẹnyin ọmọ ilẹ Igbomina ma bere eto Ijọba ibilẹ ti yin lọwọ awọn ara Ilọrin, ki ẹ le roju raye tun ilu yin ṣe pẹlu owo-ori ti ẹ ba da, nitoripe ọrọ owo kiṣe yẹyẹ rara.

Ẹtọ yin ni i, nitoripe bi ọmọde ba to ni apo, o yẹ ki a fun un, nitotọ ẹnyin na ti dagba to oju bọ, ti ẹgan kọ ẹnyin to da duro funra yin. O tilẹ yẹ ki awọn ara Ilọrin paapa ma ṣe igberaga, ti nwọn ba yan Ijọba ibilẹ fun yin wipe awọn awọn sin yin de ibiti ẹru ko ni ba yin lọjọ oni.

## Egbe Fomo Yo F'Otta

Fun apẹrẹ, abẹ awọn Ẹgba ni Abẹokuta ni Ijoba ibilẹ awọn Ọtta ti wa lati ọdunmọdun; tani ko mọ wipe oṣelu gidi ni awọn Ẹgba? Nigbati o ya wọn, awọn Ẹgba ju awọn ara Ọtta silẹ, nwọn ni ki awọn na ma ba iṣẹ itu wọn lọ funra wọn.

Nwọn ko fi ija tuka, nwọn ṣe ọrọ na ni ọrọ ọmọ ti o to ya oko ti baba si ya oko tirẹ fun un. Ni ọjọ oni, awọn Ẹgba ko le ma ṣe nkan rere ki ẹ ma ri Ọba Olọta ati gbogbo awọn ijoye Ọtta nibẹ-nwọn ti di ọmọ-iya patapata.

## Ilorin Gexi Alimi

Bi awọn Ẹgba ni Abẹokuta tiṣe huwa ọmọluwabi fun awọn ara Ọtta yi ni o yẹ ki awọn ara ilu Ilọiin ṣe ọrọ ọmọ Ọffa ati Igbomina ti nwọn ni awọn njẹ ki nwọn jẹki awọn ma ṣe Ijọba ibilẹ ti wọn, ki nwọn ma ṣe ọrọ na ni ỌRỌ AMUSIN DỌJỌKU. Ki a tete tu wọn silẹ nigbati o yẹ, ki a ba le gbayi gbẹyẹ nibẹ.

Laipẹyi ni mo ba ọrẹ mi kan fi ọrọ jomi toro ọrọ lojude Ọba Ilọrin lori ọrọ awọn ara Ọffa ati Igbomina nigbati Dokita Azikiwe wa bọ Ilọrin wo.

(Wo iyoku loju ewe kerin)

# Nwon Pa Kotu Kekeke Re Ni Ibadan

IBADAN — Ninu iwẹ ikede ijọba ipinlẹ iwọ Orun kan ti nwọn gbe jade lọsẹ yi ni a gbọ wipe nwọn pa awọn kotu-kekeke ti Ijọba ibilẹ Ibadan rẹ patapata. Idi akan ti e fa ti nwọn fi fẹ pa awọn kotu na rẹ ko ye wa rara, ijọba ko si fi ye ẹnikan.

Alaye ti nwọn ṣe nipa ọrọ awọn kotu na ni wipe awọn fẹ tun eto awọn kotu ibilẹ ṣe daradara ninu ọdun ti a bọ si yi. Ọgbẹni B.O. Olowofoyeku tiṣe minisita alamoju eto idajọ ni awọn ko fẹ eto kotu ti yio ma segesege, awọn nfẹ idajọ ti o tayanju gere ni gbogbo kotu ibilẹ.

Minisita na ni kankan kọ lo mu eto yi wa awọn fẹ ki gbogbo enia ipinlẹ Iwọ orun ma ma ri idajọ ododo laisi isaju gbà. Awọn si fẹ ki olukuluku tete ma ri wije awọn adajọ tete da ẹjọ on.

Awọn ara Ibadan si nṣe ikunsinu lori awọn kotu kekeke ti nwa parẹ na.

World's renowned top quality

JAPANESE BICYCLES




Contact your nearest local Bicycle Shop Now!

Messrs. Importers, Please Write for Import Information to:

JAPAN BICYCLE TRADE CENTER

P. O. BOX 4117 BEIRUT - LEBANON

Iwe Akoka Yoruba :

# Eto Igbeyawo Ni Ile Yoruba (3)

## Lati Owo Alufa Atilade

### Ojo Aisun Iyawo

Inawo igbeyawo bere lati ojo aisun lo. Okoyawo yio gba ilu tire, iyawo na yio gba ilu tire. Oko iyawo pelu awon egbe re ati awon aladugbo re l'okunrin, l'obinrin yio jo lo si 'le iyawo na pelu gbogbo awon ebi re yio si wa si ojude oko re lehin igbati oko re ba ti jo pada bo si ile re. Nigbati oko iyawo ba jo lo si'le iyawo re, idile iyawo yio se ni alejo. Nigbati iyawo na ba si jo de ojude oko re, awon egbe iyawo yio gba okan alejo won, sugbon iyawo ko gbodo wo 'le titi yio fi di ojo igbeyawo.

### Ojo Igbeyaowo

Ojo igbeyawo je ojo aye, ojo ogo ati ojo inawo. Lati aro ni awon onilu ti iyawo ati ti oko iyawo yio ti de si ile si ile onikaluku won. Iyawo ti o ti nro papin aso ti awon ebi ti ko wa fun eye re yio pa bambari ni ojo yi.

Lehin igbati iyawo ba we ti o si jeun tan, olutoju re yio wa mu bo si yara lati se oso fun un ati lati ro o li aso li aso. Nwon yio so ilek'e segi si i li orun, nwon yio fi oruka tabi ileke eti si i li eti, egba fadaka yio wa lorun owo re kini ati ekeji, ewon fadaka yio wa l' orun re, iyawo le ro bi aso meta po iekansoso, nwon yio si fi oja gba okokan won legbe ki o ma ba tu l'ode. Iborun kan yio wa li egbe otun ati okan li egbe osi. Nwon a wege lere ni ona ti ko fi ni le tu boro, nigbati o ba de ode.

Nigbati a nwo aso fun iyawo, gbogbo awon elegbe iyawo ati aladugbo re ti se tan, onilu papa ti nfi ilu si i, Nigbati a ba mu iyawo jade lati yara lwoso, a mu u lo ki bale ile na baba re ati iya re. Lati inu ile ni ijo dere titi nwon yio fi de ojude oko iyawo ati iwiti nwon gbe nrebi iyawo lati aro.

Bi iyawo ba ti bo si ijo, gbogbo ebi re ati awon ore re ni yio ma fi owo mo o lori lati ye e si, awon onilu ni yio ma gba owo yi.

Nigbati iyawo ba jo de ojude oko re, odu di ikare. O e to wakati kan ki nwon te pari eto ohun gbogbo ti awon elegbe iyawo yio gba: Gegebi asa ni ile Yoruba, oko iyawo ko ni lati si ni ile nigbati iyawo ba de nitorina oko iyawo yio le sinu ile kan ni adugbo.

Awon elegbe iyawo yio gba odidi adie ti a ti se pelu onje won, obi ati igo oyin kan; awon omo ile iyawo yio ka ore ti won, adie kan, onje, obi ati igo oyin, bena ni awon obinrin ile iyawo yio gba ti won pelu, lehin na, ni awon yio te jeki nwon gbe iyawo wo ile.

Awon obinrin ile oko iyawo yio bu omi si ese iyawo, lehin na nwon yio gbe iyawo ni konkolerun pelu gbogbo aso ati oso re wo inu ile lo si gbangba ita ile na; nibiti nwon yio gbe tu gbogbo aso iyawo na sile, nwon yio si we iyawo na ni 'hoho loju gbogbo ara ile re lati fi han won wipe iyawo na pe, ko si abuku kan lara re. Nigbati a ba nwe iyawo na, on yio fi owo mejeji bo oju re.

(Koiti pari)

## AWON KOSEKU KOSEYE

(O bere loju ewe Keta

### Se O Ti Nre Yin?

Ore mi ti mo mba soro na ni fi nmu okan mi kuro ninu wipe awon Igbomina yio gba Ijoba ibile ti won loto, o ni awon ti o je pataki ninu awon oloye ti Igbomina ti mu okan won kuro nibe patapata, ore mi na ni a fi awon edomode inu won ti nwon nfe ki enyin oniwe irohin ma logun oro won kiri ni o tun gbe irohin eke kiri wipe ki a ba won tee.

Oro ore mi omo Ilorin yi mu mi ki nronu wo pupo, emi na si ro oro na lo gara O mu mi niran orisirisi awon nkan ti mo ri ka ninu gbogbo iwe ti awon omo Igbomina nile ati l'Oke Okun ti ko si mi nipa oro awon agbalagba ati awon ijoye ilu Offa ati Igbomina ti oro na se nre. Ti o ba soro ilu won let awon miran, nwon a gbe eti kuro kuro nibe bi eni wipe nwon ko gbo rara.

### Oro Ika

Oro imoran bayi dabi igbati awon Yoruba ba nso wipe a nlo fi oro ika lo ika. Ti a ba se be, o dabi eni pe a si ntan awon ara ilu wa je ni gbogbo re ri loju e m i Olofintoto.

Se gbogbo enyin okawe mi wa ri wipe otito oro ti emi Ayiluka so ninu iwe irohin Eleti-Ofe ni nkan bi odun kan ati osu meta sehin, ti mo ni ORO AWON ARA ILORIN PELU AWON IGBOMINA DI ORO SURU?

Emi alara ti mo so be mo nkan ti mo nso nigbana ki Ogbeni kan ti o pe ara re ni Odekunle to so wipe alayonuso ni mo nse. Oro Ogbeni na ko dun mi rara nitoripe oju re ko tele ketekete oro ti emi Olofintoto ri nipa oro ijoba ibile ti awon omo Igbomina pelu awon omo Offa nfe fun ilosiwaju ilu won.

### Eke Ni Oju O Ti

Mo ro wipe idi re ni yi nitoto ti awon odomode kan fi nso wipe awon ti di Oloye awon si ti di akowe-agba fun awon e g b e oselu Olomi (NPC), nitorina awon a pase fun a w o n oba ilu gbogbo ilu Igbomina ati awon ara Offa, ki nwon ma ko owo - ori ti nwon bo gba fun awon ara Ilorin ma a fi ni Kaduna ni awon nko gbogbo owo na lo. Tani w a ni Ilorin, tani wa ni Kaduna? Mo sebi awon ti nwon nfe mu yin sin tomo tomo ni nwon wa nibe.

### Ni A Fi Lo'ka

Oro ilu Ilorin pelu awon Igbomina gba elege pupo nitoripe bi awon kan ti ngbiyanju wipe ki oro na le ni iyanju ni awon kan nko ina mo kikan kikan ni awon ARIJE NINU MADARU na ti wa lodo awon omo Igbomina ni nwon wa ninu awon omo Ilorin ni opolopo.

Emi Olofintoto Eleti-Ofe mo dire ninu awon baba ARIJE-NINU--MADARU yi sugbon (ko ni da oruko won, ma fi oruko bo won ni asiri, Iyoku di ose ti mbo)

**Plushes Velvet Velveteen Damasks & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, Faji Market

LAGOS NIGERIA

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka

### Se Odun Iyi Ni ?

Mo ki gbogbo ẹnyin ọkawe mi ku ọdun titun ti a ṣẹṣẹ bọ si yi. Ṣe gbogbo yin na mọ wipe igbakugba ti a ba ri ni ni owurọ ẹni. Baba mi ti sọ fun mi wipe ọdun ni a ma fi nyin ọdun.

Nigbati emi na ṣe ndagba mo ṣe akiyesi wipe ọdun ni a ma fi nyin ọdun. Emi ko le gbagbe awọn ọdun ti mo nlọ si ile ẹkọ, ti a ki ji iwe idawo, ti awọn tiṣa wa nkọ wa bi a nsọ otitọ.

Emi ko le gbagbe ọ d u n igbati awọn obi wa nfi aṣọ abọwọde sọdun, ti nwọn ko kọ wa ni ọkan-juwà, ti owo si niyi. Ko si ikorira nigbana.

### Tabi Odun Ete?

Ẹnikan kọwe si mi wipe ki mba awọn obinrin Yoruba ti wọn fẹran lati ma ba enia ti ọba ṣe ẹsọ ọdun titun sọrọ. Obinrin ti o kọwe na ni awọn obinrin wa fẹran lati ma bu awọn ti ko ba wọ ẹsọ to wọn tabi ki nwọn ko gofu si gbogo ara bi were.

Ko si ibawi ti mo le ba awọn obinrin wa yi wi ju wipe iwa ni yio kilọ fun oniwa. Ẹni ma ku re, ọwọ ara re ni yio fi fa a. Ti awọn na ko ba fẹ ṣe ọdun yi ni ọdun ẹtẹ, ki nwọn ṣe ipinnu wipe awọn ko ni ma kẹgan ẹnikeji wọn

### Taju Bi Abiodun

Ni owurọ ijarun, ki a to ma ṣe wahala aisun ọdun titun ni mo gbọ wipe iyawo ọre mi Ọgbẹni Taju Thompson, ọga-agba ibiṣe Eleti-Ọfẹ, ti orukọ re nje Sidikatu bi ọmọkunrin jojolo si ile dokita kan l'Ẹkọ. Emi Ayiluka ba iya ati baba ọmọ na yọ pupọ, mo si fẹ ki nwọn mọ wipe lati inu iya re ni ọmọ na ti gbọrukọ wa—ABIỌDUN ni emi sọ ọ.

### Adegbenro Ni Balogun Owu

Mo gbọ wipe IWE—ARAMU—KANDU kan ni Ọgbẹni Tijani Aderinọla ti o ni Alhaji D S Adegbenro gba oye Balogun Owu lọwọ on ni Abẹokuta ngbe kiri wipe awọn alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Ọrun ti gba oye Balogun na lọwọ Alhaji Adegbenro; nwọn ni ẹnikan ko gba oye Balogun na lọwọ rẹ.

Emi Ayiluka paapa mo wipe Alaiyeluwa Ọba Olowu Gbadela keji ni o fi oye na da ọmọ ilu rẹ lọla, on na o si ni ẹtọ lati rọ ọ loye ewo ni si awọn alayọnuṣọ. Ẹ sọ fun Tijani ko fi IWE-ARAMU ti o ngbe kiri pamọ s'apo di igba miran, ki o lọ wa iṣọ ṣe.

## Iseyin Omo Abedi

Mo ti de ilu Iseyin ti pe sugbọn o si gbọgbọ nkan ọrọ ilu ti o nlọ ni ilu na ti emi Ayiluka ki gbọ. Mo gbọ ti aawọ ferefe kan larin t o wa n awọn kans o ilu na, mo si gbọ higbati awọ ise iwin (ẹnkuari) ọrọ Ọba Aseyin, Raji Adebọ vale ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Ọrun, ni ki nwọn wa kiro ilu lọ si ebutẹ won Ilaje ni Okitipupa.

## Ilu Eye Kiki Egan

O dun mi pupọ fun Ọba Asẹyin na nitoripe ọrọ a ngbe eti ebute sọ pupọ oa ti o ti nje iyan pẹlu amala elubọ-iṣu o sọro ki gari Okitipupa to mọ o lara; ẹran igbẹ mbẹ ni Iseyin, Iganna ati Oke-Iho ti Ọba Asẹyin ti fi nse ọbẹ pẹlu ẹgusi lati ojọmọjọ o sisiyi Iyawo rẹ ni lati kọ bi nwọn ti nse ẹja ọbẹ ni Ebute Irele ati bi a ti ngbe e ka'ṣa ti ki fi fọ s nu sisun.

Ọrọ i nsun rara, a nju sẹkẹrẹ ati aro ko si mọ eyi mọ kamọmọ. Ṣe ẹnyin na rii wipe oye ki kanu Ọba Asẹyin na. Mo gbọ wipe ọna lewabi kan ni ilu Iseyin ti dide sọrọ na wipe awọn oko yọ Ọba awọn loye ati wipe ko awọn si ẹsẹ ti Ọba Asẹyin ṣẹ ki a to lẹ ẹ kuro nilu.

(Wo iyoku ni oju ewe Kejọ)

CARSON PAINTS AND VANISHES











SOLE AGENTS
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, Balogun Street, Lagos.

# Ayiluka Ni:

## Ẹgbẹ Alakuko Di Alalikali

(O bẹrẹ loju ewe karun)

Ọrọ rogbodiyan awọn ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti Ibadan ti o ngbona si lojojumọ, ti awọn janduku ti ti o wa ninu ẹgbẹ na nfọ iga aga mọ ara wọn lori jẹki nmran wipe ọpọlọpọ awọn ỌMỌ ALIKALI ti a mọ l'Eko ti ba awọn baba alagbara inu ẹgbẹ na lọ si Ibadan nitori ọnjẹ ọjọ wọn. Mo gbọ wipe oloye Mọjidi Agbaje ko le gbagbe akan ti awọn ọmọ Alikali inu ẹgbẹ wọn fi oju rẹ ri ni Oke Mapo ni irọlẹ ọjọ Satide ijẹjọ.

Ọrẹ mi bi o ba fẹ ma ba wọn ṣelu ti nwọn nṣe ni aiye isisiyi, ki o wa si Eko wa haya awọn ọmọ Alalikali ni Popo-Aguda, iya ko ni jẹ ọ mọ. Awọn ọmọ Alalikali ni nwọn ni awọn oṣelu isisiyi. Nitotọ ko si iṣẹ pupọ fun awọn ọmọ Alalikali ni Eko tobẹ mọ ni Opopo Campus a fi ki a ma ṣe ọlẹ-atẹlẹ-alufa kiri.

## Owo Meka

Mo gbọ wipe awọn alaṣẹ ijọba Mẹka ti gbe ofin kan jade wipe awọn ko fẹ ki awọn ara wa ma wa ṣe owo ṣiṣe ninu awọn, nwọn ni ẹsin ti wọn wa sin nilu na ni ki nwọn tẹju mọ. ti nwọn ba ti gun Oke Arafa wọn tan, ki nwọn jade nilu ni were. Abọ ọrọ ni a nsọ fun ọmọluwabi, iyoku wa ninu emi Ayiluka.

# £73 Million For Nigeria

LONDON— November proved another big month for Britain's purchases from Nigeria, scoring a £2 million increase over the same month a year ago, while the eleven month total has topped the previous year's by some £4 1/2 million.

Figures just published by the Board of Trade in London reveal some striking increases – cocoa up by £1/2 million over the year, oilseeds by £2 million, cotton by £3/4 million and petrol by £3 1/2 million. over

The total of all Britain's imports from Nigeria in the first eleven months of 1962 was £68,473,766 which rose to £73, 114, 127 in the same period of 1963.

The month of November alone is equally impressive the £4, 896, 889 of 1962 rising to £6, 953, 022 in 1963.

# British Minister Is Touring Nigeria

LAGOS—Mr. Richard P. Hornby, M.P. Parliamentary Under-Secretary of State, Commonwealth Relations Office, is in town on his two weeks tour of West Africa. At Ikeja Airport he was met at the VIP Chalet by the Acting British High Commissioner, Mr RWD Fowler CMG., where he answered questions by newspaper reporters and posed for press photographs

After signing the President's and Prime Minister's Visitors' Books he was in private conversations with the staff of the British High Commission, British Information Services and the British Council in Lagos.

Yesterday he visited Ibadan he had discussions with Western Region Ministers and visited the Universities of Ibadan and Ife. In Enugu today for the weekend, Mr Hornby has accepted invitations to dine with the Premier and the Governor of the Eastern Region. He will spend the 7th 8th January in Kaduna and Zaria calling upon the Governor and on Northern Region Ministers and having lunch with the Vice-Chancellor of Ahmadu Bello University.

Returning to Lagos on the 8th January, Mr. Hornby has accepted invitations to call upon Federal Government Miniters and to visit the House of Representatives.


**MERCEDES — BENZ**

*Vehicles are Built to last, to give many years, and many miles of trouble-free, economical Service.*



**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS, APAPA, IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT-HARCOURT, ABA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos Phone 23370; Editor; (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O Box 467